


YORUBA

# Dídá ààbò bo ìlera àwon omodé nísisìnyí àti fún ọjọ́ iwájú

Àlàyé síwájú síi nípa àwon àjẹsára

selondonics.org/childrenshealth

nhs.uk/conditions/vaccinations

SCAN ME

# Kílódé tí àwon ọmọdé nílò àwon àjẹsára?

**Àwon àjẹsára máa ń dá ààbò bo àwon ọmọdé kúrò lọ́wọ́ àwon àrùn tó lè gba ẹ̀mí ènìyàn nígbàtí wọ́n bá ṣì kéére, títí gbogbo àwon ọdún won ní ilé-ìwé áti gẹ́gẹ́ bíi àgbàlagbà. Káàkiri àgbáyé, àwọn àjẹsára ti gba ẹ̀mí míllíọ́nù àwọn ènìyàn là. Àmọ́, bí àwọn ènìyàn bá dẹ́kun láti máa gba àwọn àjẹsára, ó ṣeéṣe fún àwọn àjàkálẹ̀ àrùn láti tètè tàn kálẹ̀ lẹ́ẹ̀kansíi.**

## Báwo ni àwọn àjẹsára ṣe ń ṣiṣẹ́?

Àwọn àjẹsára máa ń ṣiṣẹ́ nípa fífi ara jọ ìṣesí kòkòrò àrùn (wíwọlé àti ìdàgbàsókè kòkòrò àìfojúrí, bíi fáírọ̀sì tàbí baktéríà, nínú ara) àti kíkọ́ ara láti ṣẹ̀dá ṣọ́jà pátákì tí à ń pè ní ṣọ́jà ara tó ń dá ààbò bo ara kúrò lọ́wọ́ àrùn.

Ó jẹ́ ohun tí ó túnbọ̀ ní ààbò fún ara làti mọ èyí nípasẹ̀ àjẹsára ju níní àrùn náà kí a sì tọ́jú rẹ̀. Ní kété tí ara bá ti kọ́ làti bà àrùn jà nípasẹ̀ àjẹsára, ó ń sábà dá ààbò bo ọmọ rẹ fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún.

## Ó ń dá ààbò bo àwon ọmọdé kúrò lọ́wọ́ àrùn àti àìsàn

Gẹ́gẹ́ bí Àjo Ti ìlera Ní Àgbáyé World Health Organization (www.who.int) ti wí àwon àjẹsára máa ń dènà ikú àwon èèyàn tí ó tó míllíọ́nù 3.5 ní ọdún kọ̀ọ̀kan kúrò lọ́wọ́ àwon àrùn bíi diphtheria, bíi àrùn wayínlù, ikọ́ àwúbì. ọ̀fìnkìnàti olóde.

Láti ìgbà tí a ti gbé àwọn àjẹsára jáde ní UK, àwọn àrùn bíi smallpox àti wayínlù, tí wọ́n ti ṣe ikú pa tàbí sọ ọ̀pọ̀ míllíọ́nù àwọn èèyàn di aláàbọ̀ ara, ló ti wá pòórá báyìí tàbí tí a kò tílẹ̀ fẹ́rẹ̀ rí wọn mọ́ rárá. Àwon àrùn míràn bíi olóde àti diphtheria ti já wálẹ̀ tó ìdá 99.9% láti ìgbà tí a ti gbé àwọn àjẹsára wọn jáde.

**Àmọ́, bí àwọn ènìyàn bá dẹ́kun láti máa gba àwọn àjẹsára, ó ṣeéṣe fún àwọn àjàkálẹ̀ àrùn láti tètè tàn kálẹ̀ lẹ́ẹ̀kansíi.**

## Kí ni ìwé ìléwọ́ yìí wà nípa?

Ìwé ìléwọ́ yìí ń ṣàlàyé síwájú síi nípa àwon àjẹsára (tí a tún mọ́ gẹ́gẹ́ bíi gbí gba abẹ́rẹ́ àjẹsára) tí à ń fún àwon ọmọdé ní ọ̀fẹ́ lórí ètò NHS àti nígbàtí wọ́n máa gbà á. Ó ṣe pàtàkì láti tètè gba àwon àjẹsára nígbà tó yẹ fún ààbò tó péye, ṣùgbọ́n bí ọmọ rẹ bá ti pàdánù láti gba àjẹsára kan, o lè kàn sí Dókítà rẹ láti gbà á kí ó pé.

# Àrùn rọpárọsẹ̀ àti MMR
# àwon àjẹsára gbà á kí ó pé ní London

**Àwon ọmọdé pẹ̀lú ọjọ́ orí 1 sí 11 ní London tí wọn kò tîi gba àwọn àjẹsára wọn ní pípé ni à ń fún ní ànfàní láti gba àwon àjẹsára fún àrùn rọpárọsẹ̀ àti MMR nípasẹ̀ Dókítà oníṣẹ́ abẹ, àwọn ilé ìwé aláàkọ́bẹ̀rẹ̀, àti àwọn ilé ìwòsàn ìjọba kékéré ní àdúgbò.**

## Kílódé tí àwon àjẹsára láti dá ààbò bo àwon ọmọdé kúrò lọ́wọ́ MMR àti àrùn rọpárọsẹ̀ ṣe pàtàkì tó bẹ́ẹ̀?

Ní 2022, fáírọ́sì kòkòrò àrùn rọpárọsẹ̀ ni wọ́n rí nínú àwọn omi ìdọ̀tí tí a bu díẹ̀ lára rẹ̀ ní London, tó tọ́ka sí pé fáírọ́sì náà ti ń tàn láàrin àwọn èèyàn. Nígbàti ìtọpinpin ní àìpẹ́ yìí dáàbá rẹ̀ wípé ìtànkálẹ̀ rẹ̀ ti dínkù, àwon tí won kò tîi gba àjẹsára ní pípé tàbí àwọn tí ara wọn kò ṣe déédé sí gbígba àwọn àjẹsára, ṣì lè wà nínú ewu kíkó àrùn rọpárọsẹ̀.

Àwọn àkọsílẹ̀ ti pọ̀ síi nípa àrùn olóde ní London ní ọdún yìí (2023). Káàkiri England, ní òdiwọ̀n 1 nínú 10 àwọn ọmọdé ni kò tíi gba àjẹsára MMR ní pípé, pẹ̀lú àwọn agbègbè kan ní London tí wọ́n ní èyí tó kééré bíi 2 nínú 5, tó ńfi ẹgbẹẹgbẹ̀rún àwon ọmọdé sínú ewu kíkó àrùn olóde, ní pàtó àwọn tó lè tètè kó àrùn, àti àrùn náà tí ó ń tàn kiri láì ní àjẹsára ní àwọn agbègbè.

## Ṣe àwọn àjẹsára MMR àti àrùn rọpárọsẹ̀ kò léwu?

Bẹ́ẹ̀ni, wọ́n ní ààbò tó pọ̀ púpọ̀ tí wọ́n sì ti dá ààbò míllíọ̀nù àwon ọmọdé ní àgbáyé.

## Ṣe àsopọ̀ kankan wà láàrin àjẹsára MMR àti àrùn ọ̀dọ̀yọ̀?

Kò sí ẹ̀rí wípé àsopọ̀ kankan wà láàrin àjẹsára MMR àti àrùn ọ̀dọ̀yọ̀. Ọ̀pọ̀ àwọn ẹ̀kọ́-kíkọ ti ṣe ìwádìí èyí.

## Báwo ni àwon àjẹsára ti ṣe di gbígbà fún àwon ọmọdé?

Àwọn àjẹsára méjèèjì ni a ń fún àwon ọmọdé pẹ̀lú abẹ́rẹ́ sínú iṣan ní itan tàbí ní òkè apá.



# Ọjọ orí wo ni àwon ọmọ mi nílò láti gba àjẹsára wọn?

| Ọjọ́ orí | Abẹ́rẹ́ Àjẹsára | Ńdá ààbò lòdì sí |
|---|---|---|
| Ọ̀sẹ̀ 8 | **Àjẹsára 6 nínú 1** (ìwọ̀n lílò 1) | – **Diphtheria, Jẹ̀dọ̀jẹ̀dọ̀B, Hib** (Irúfẹ́ B Ọ̀fìnkìn) **Àrùn rọpárọsẹ̀ , Ẹ̀yi, Ikọ́ àwúbì** (pẹ́tússísì) |
| | **Rotafáírọ́ sì Àjẹsára** (ìwọ̀n lílò 1) | – **Rotafáírọ́ sì** |
| | **YírùnyírùnB** (ìwọ̀n lílò 1) | – **Kòkòrò Àrùn Yírùnyírùn Ẹgbẹ́ b** |
| Ọ̀sẹ̀ 12 | **Àjẹsára 6 nínú 1** (ìwọ̀n lílò 2) | – (Wo òkè) |
| | **Rotafáírọ́ sì Àjẹsára** (ìwọ̀n lílò 2) | – **Rotafáírọ́ sì** |
| | **Pneumococcal (PCV) Àjẹsára** | – **Òtútù Àyà** |
| Ọ̀sẹ̀ 16 | **Àjẹsára 6 nínú 1** (ìwọ̀n lílò 3) | – (Wo òkè) |
| | **YírùnyírùnB** (ìwọ̀n lílò 2) | – (Wo òkè) |
| Ọdún 1 | **Hib/YírùnyírùnC** | – **Hib** (Ọ̀fìnkìn Irúfẹ́ B), **YírùnyírùnC.** |
| | **MMR** (ìwọ̀n lílò 1) | – **Àrùn olóde, Ṣegede, Rubẹ́llà** |
| | **Kòkòrò òtútù àyà (PCV)** (ìwọ̀n lílò 2) | – **Òtútù Àyà** |
| | **YírùnyírùnB** (ìwọ̀n lílò 3) | – (Wo òkè) |
| Oṣù 18 | **MMR** (ìwọ̀n lílò 2) fún àwọn ọmọdé tí wọ́n ńgbé ni púpọ̀ nínú àwọn Agbègbè South East London | – **Àrùn olóde, Ṣegede, Rubẹ́llà** |
| Ọdún 2-16 | **Àjẹsára Ọ̀fìnkìn** (ní ọdọọdún) | – **Ọ̀fìnkìn** (Ọ̀fìnkìn) |
| Ọdún 3 & Oṣù 4 | **4 nínú 1** (Ṣáájú-Ilé Ìwé Gbígbàsára) | – **Diphtheira, Àrùn Ẹ̀ yi, Ikọ́ Àwúbì**, **Àrùn rọpárọsẹ̀** |
| Ọdún 12-13 | **Àjẹsára HPV** | – **Fáírọ́ sì Wọ̀ nwọn Ara** |
| Ọdún 14 | **3 nínú 1** (Gbígbàsára Ọ̀ dọ́) | – **Àrùn Ẹ̀ yi, Diphtheria, Àrùn rọpárọsẹ̀** |
| | **YírùnyírùnACWY** | – **Yírùnyírùn, Ẹ̀ jẹ̀dúdú** |

# Irú àwọn àrùn wo ni àwọn àjẹsára wọnyí ń dá ààbò ọmọ mi lòdì sí?

## MMR
(Àrùn olóde, Ṣegede, Rubẹllà)

Àrùn olóde àti rubẹllà ló máa ń sábà bẹrẹ pẹlú àwọn àpẹẹrẹ bíi ọfìnkìn, tí kùrukùru ara sì máa tẹlé e. Ní àwọn ìgbà tí kò wọ pọ àrùn olóde lè tẹsíwájú sí gìrì, ìfọjú, òtútù àyà àti yírùnyírùn, àti pé nígbàmíràn ó lè gba ẹmí. Rubẹllà ni ó léwu púpọ fún àwọn tó lóyún, tó ń kó ìṣòro bá ìkókó tí wọn kò tîì bí. Ṣegede máa ńfa wíwú tó ńdun èèyàn ní ẹgbẹ ojú kan àti ní àwọn ìgbà tí kò wọpọ ó lè ṣokùnfa yírùnyírùn.

## YírùnyírùnB + YírùnyírùnACWY
Àwọn àrùn àkóràn yírùnyírùn lè le púpọ, tó ń ṣokùnfa yírùnyírùn àti ẹjẹ dúdú (sepsis). Ní àwọn ìgbà tí kò wọ pọ wọn lè gba ẹmi.

## Numokókàlì
Kòkòrò àrùn numokókàlì lèlè le púpọ tó ń tẹsíwájú di òtútù àyà, ẹjẹ dúdú àti yírùnyírùn.

## Tẹtánọsì
Tẹtánọsì jẹ ipò tí ó lágbára, tí ó léwu fún ẹmí tí ó máa ń wáyé nípasẹ kòkòrò àárùn tí ó ń wọnú egbò. Ó lè fa ìgbọn líle, ìrora ìfúnpọ iṣan, ìṣòro mímí, ìgbóná gíga, líla àágùn, ọkàn sísáré àti dídákú.

## Ikọ àwúbì
(tí a tún ń pè ní pertussis)

Ikọ àwúbì jẹ àrùn àkóràn ti ẹdọ fóró àti ọnà afẹfẹ ní inú tí ó lè jẹ kí àwọn ìkókó àti àwọn ọmọ wẹẹrẹ máa ṣe àìsàn púpọ. Ní àwọn ìgbà tí kò wọ pọ ó lè gba ẹmi.

## Rotafáírọsì
Rotafáírọsì jẹ àrùn àkóràn kan nínú ikùn tí ó máa ń sábà ṣàkóbá fún àwọn ìkókó àti àwọn ọmọ wẹẹrẹ, ó ń ṣokùnfa ìgbẹ gburu àti èèbì, inú rírun àti ara gbígbóná.

## Àrùn rọpárọsẹ
Àrùn rọpárọsẹ lè ṣokùnfa àwọn àpẹẹrẹ fẹẹrẹfẹ, bíi ọfìnkìn ṣùgbọn ní àwọn ìgbà tí kò wọ pọ ó lè tẹsíwájú sí ara rírẹ (rọpárọsẹ).

## Diphtheria
Diphtheria jẹ àrùn àkóràn kan tó le púpọ tí ó sì máa ń sábà ṣàkóbá fún imú àti ọfun àti nígbàmíràn àwọ ara. Ó lè gba ẹmí, ní pàtó láàrín àwọn ọmọdé, tí a kò bá tètè ṣe ìtọjú rẹ.

## Jẹdọjẹdọ B
Jẹdọjẹdọ B jẹ àrùn àkóràn ti ẹdọ tí ó máa pẹ tó oṣù 1 sí 3. Ọpọ àwọn èèyàn ni kò kí ńrí àpẹẹrẹ àrùn kankan tàbí kí wọn ríi fẹẹrẹfẹ ṣùgbọn ní àwọn ìgbà tí kò wọ pọ ó lè burú jáì kí ó sì pẹ tayọ oṣù 6. Jẹdọjẹdọ tó burú jáì Hep B lè di líle bí a kò bá tètè ṣe ìtọjú rẹ.

## Hib B
Haemophilus influenzae typ b (Hib) jẹ irú kòkòrò àrùn tó lè ṣokùnfà àwọn àrùn àkóràn tó lè ṣe ikú pani. Àwọn ìkókó àti àwọn ọmọ wẹẹrẹ ló ń sábà máa ń wà nínú ewu ṣíṣe àìsàn jù.

## Ọfìnkìn
Ọfìnkìn lè jẹ àìsàn tí kò dára fún àwọn ọmọdé tí ó sì lè tẹsíwájú sí ìṣòro púpọ tó le ṣe àkóbá fún ẹdọ fóró àti ọnà afẹfẹ inú, gẹgẹ bíi bronkáítìsì àti òtútù àyà.

## HPV
Human papillomavirus (HPV) ni orúkọ tí a fún kòkòrò àrùn tí wọn wọ pọ, díẹ nínú wọn ni àwọn tí à pè ní "ewu gíga" nítorípé wọn ní àsopọ pẹlú bí àwọn àrùn jẹjẹrẹ ṣe ń yọ jáde, gẹgẹ bíi jẹjẹrẹ ojú ara obìnrin, jẹjẹrẹ ibi ìyàgbẹ, jẹjẹrẹ okó, àti jẹjẹrẹ orí àti ọrùn. Irú àwọn míràn lè ṣokùnfa àwọn àìsàn bíi wọnwọn tàbí wọnwọn ẹsẹ.

# Kí ni
# àwọn ohun tí kò dára tó ń farahàn látàrí àwon àjẹsára
# fún àwon ọmọdé?

**Àwon ọmọdé tó kééré sí ìdá 10% níye máa ń ní ìrírí àwọn ohun tí kò dára tó ń farahàn tí ó máa ńtó bíi 2 tàbí ọjọ́ 3 lẹ́yìn àjẹsára.**

Àwọn ohun tí kò dára tó ń farahàn lè jẹ́:

- **Wíwú, pípọ́n àti níní ìmọ̀lára ríro yíká ibi ojú abẹ́rẹ́**
- **Níní ìmọ̀lára àìlera ránpẹ́ tàbí ara tó ń gbóná**
- **Níní ìmọ̀lára kíkanra, ẹkún sísun tó pọ̀síi tàbí ìnira, àìbalẹ̀ ara**
- **Èébì àti àìnífẹ̀sí oúnjẹ jíjẹ fún ìgbà díẹ̀**

Àwọn ọmọdé míràn lè ní ìrírí àwọn ohun tó ń farahàn tí kò wọ́ pọ̀ rárá - fún àpẹẹrẹ ìrírí kùrukùru ara máa ńwà fún 1 nínú gbogbo ìwọ̀n òògùn lílò 24,000 àjẹsára MMR tí a fúnni.
Bá Dókítà rẹ sọ̀rọ̀ láti mọ̀ síi nípa ìrírí àwọn ohun tó ń farahàn tí kò wọ́ pọ̀ rárá. Ó ṣe pàtàkì láti rántí àwọn nnkan míràn tó ṣeéṣe kí ó farahàn látàrí kíkó àwọn àrùn àkóràn, gẹ́gẹ́ bíi àrùn olóde, ṣegede àti rùbẹ́llà, jẹ́ àwọn tó le púpọ̀.

## Kí ni kí ńṣe tí ọmọ mi bá ń ní ìrírí àwọn wọ̀nyí tàbí àwọn nnkan míràn tó lè farahàn?

Àwọn nnkan míràn tó lè farahàn fẹ́ẹ̀rẹ́fẹ́ ni ó ṣe é tọ́jú pẹ̀lú paracetamol fún àwon ọmọdé f.a. Calpol. Tí o bá ń ronú, tàbí tí àwọn nnkan míràn tó lè farahàn bá wà lára ọmọ rẹ lọ́wọ́lọ́wọ́, bá Dókítà rẹ sọ̀rọ̀.



# Kí ni ó wà nínú àwọn àjẹsára àti ṣé wọ́n ní ààbò?

## Kí ni àwọn èròjà tó wà nínú àjẹsára?

Kókó èròjà èyíkéyìí àjẹsára ni ìwọ̀nba díẹ̀ nínú kòkòrò àrùn tí a ti pa, aláìlágbára, tàbí tí èyà aṣéjáde kòkòrò tó ń fa àrùn náà. Àwọn wọ̀nyí ni à ń pè ní ántíjẹ̀n. Àwon àjẹsára tuntun míràn ní àwọn ìtọ́sọ́nà fún ara láti ṣe àgbéjáde àwọn ántíjẹ̀n, dípò ántíjẹ̀n fúnrarẹ̀ gangan.

Àwon àjẹsára nígbàmíràn ní àwọn èròjà míràn tí ó máa mú kí àjẹsára ní ààbò kí ó sì tún múnádóko.

## Ṣe èyíkéyìí àwọn àjẹsára ní èròjà ẹran ẹlẹ́dẹ̀ nínú?

Àwon àjẹsára míràn ní èròjà ẹran ẹlẹ́dẹ̀ nínú láti mú dájú pé àjẹsára náà ní ààbò kí ó sì múnádóko nínú ìtọ́júpamọ́ rẹ̀. Bí o kò bá fẹ́ kí ọmọ rẹ gba àjẹsára tí ó ní èròjà ẹran ẹlẹ́dẹ̀ nínú fún èrèdí ẹ̀sìn àti ṣíṣọ́ oúnjẹ ní jíjẹ, bá akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ ètò ìlera rẹ sọ̀rọ̀ nípa àwọn àjẹsára míràn tì ó ṣeéṣe kí ó wà.

## Ṣé àjẹsára ní ààbò fún àwon ọmọdé?

Ọ̀pọ̀ mílíọ́nù àwon ọmọdé ní UK àti ní àgbáyé ti gba àwọn àjẹsára lòdì sí àwọn àrùn àti àìsàn líle- tí wọ́n sì ti wà ní ààbò fún ìdí èyí. Gbígba àjẹsára bákannáà ń dá ààbò bo ìdílé rẹ, àwọn ọ̀rẹ́ àti ní òde àwùjọ, ní pàtàkì àwọn tí wọ́n lè tètè kó àrùn.

Gbogbo àwọn àjẹsára ni wọ́n máa ń dán wò ní orísirísi ọ̀nà fún ààbò nípa ti òfin kí a tó gbé wọn jáde. Ní kété tí a bá ti gbé àjẹsára jáde ní UK, Àwọn Àjọ Fún Àmójútó Àwọn Òògùn àti Ìtọ́jú Ìlera (MHRA) máa ńṣe ìtọpinpin lórí rẹ̀ fún èyíkéyìí àwọn ohun tó ń farahàn tí kò wọ́ pọ̀ rárá.

## Ṣé ó ní ààbò fún ọmọ mi láti gba orísi àwọn àjẹsára lẹ́ẹ̀kanṣoṣo?

Ìwádìí ti fi hàn wípé ààbò wà láti lè gba orísirísi àwọn abẹ́rẹ́ ní ìgbà kannáà tí ọmọ rẹ yíò sì ní ààbò kúrò lọ́wọ́ àwọn kòkòrò àrún líle.

## Níbo ni mo lè lọ fún àlàyé síwájú síi?

Bí o bá ní ohun tó ń kọ́ ẹ lóminú, ò ń ṣiyèméjì tàbí àwọn ìbéèrè nípa àwọn àjẹsára àti ààbò wọn tàbí àwọn ohun tí kò dára tó ń farahàn, jọ̀wọ́ bá Dókítà tàbí akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ ètò ìlera NHS rẹ sọ̀rọ̀.

Àwọn ẹ̀rí sáyẹ̀nsì púpọ̀ wà lórí ayélujára láti ọ̀dọ̀ àwọn ilé iṣẹ́ tó jẹ́ aṣíwájú lágbayé lórí ìlera àti ìtọ́jú ní ibí yìí ní UK àti níbòmíràn, bíi Àwọn Àjọ Àgbáyé Fún Ètò Ìlera, àwọn NHS àti Yunifásítì Oxford.

Àwọn ìròyìn búburú nípa àwọn àjẹsára lè tàn káàkiri nígbà púpọ̀ lórí ayélujára, ní pàtàkì nípasẹ̀ àwọn médíà ìbánidọ́rẹ̀ẹ́. Wọ́n lè má dá lórí ẹ̀rí sáyẹ̀nsì tí ó sì ṣeéṣe kí ó fi ọmọ rẹ sí ewu àrùn líle.

**Gbígba àjẹsára jẹ́ ohun tó ṣe pàtàkì jùlọ tí a lè ṣe láti dá ààbò bo ara wa àti àwọn ọmọ wa kúrò lọ́wọ́ àìlera.**

**O lè ṣàwárí síwájú síi lórí wẹ́bsaìtì NHS:**

www.nhs.uk/conditions/
àwon àjẹsára gbígba/èrèdí-tí-àjẹsára-gbígbà-fi-
ní-ààbò-àti-pàtàkì

# Bí a ti lè gba àwon àjẹsára tó pẹ̀lú àwon àjẹsára tó ti yẹ kí á gbà

## Ta ni ó lè gba àwon àjẹsára NHS ní ọ̀fẹ́ẹ̀?

Gbogbo ọmọdé ni ó ní ànfàní sí gbígba àwon àjẹsára NHS, ní ọ̀fẹ́. Sọ̀rọ̀ pẹ̀lú Dókítà rẹ tàbí kí o ṣàyẹ̀wò ìwé pupa ọmọ rẹ láti ríi bóyá ó ti gba àwọn àjẹsára rẹ̀ ní pípé ní ìgbà tó yẹ.

## Ǹjẹ́ ọmọ mi nílò láti forúkọsílẹ̀ pẹ̀lú Dókítà láti lè gba áwọn àjẹsára wọn nígbà tó yẹ?

Bí ọmọ rẹ kó bá tíì forúkọsílẹ̀ pẹ̀lú Dókítà, wọ́n ṣì ní ànfàní sí áwọn àjẹsára ọ̀fẹ́. Ẹnikẹ́ni ní Ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì ni ó lè forúkọsílẹ̀ pẹ̀lú Dókítà oníṣẹ́ abẹ, ní ọ̀fẹ́. O kò nílò ẹ̀rí àdírẹ́ẹ̀sì ibí kankan tàbí ipò ìwọlé-wọ̀de, Ìdánimọ̀ tàbí nọ́mbà NHS. O lè ṣàwárí Dókítà oníṣẹ́ abẹ ní: **www.nhs.uk/service-search/find-a-gp**

## Níbo ni mo tún ti lè rí àfikún àlàyé síi nípa gbígba àjẹsára ọmọdé?

Jọ̀wọ́ kàn sí Dokítà oníṣẹ́ abẹ, tàbí kí o wo ayélujára ní:

**selondonics.org/childrenshealth**

**nhs.uk/conditions/vaccinations**

SCAN ME

### Àmọ̀ràn ìlera gbogboogbò nígbàtí ọmọ rẹ bá ńṣe àìsàn

Áwọn ọmọ wẹẹrẹ máa ń sábà ṣe àìsàn – ó jẹ́ ara ìdàgbàsókè. Àmọ́ ó lè jẹ́ wàhálà fún àwọn òbí àti àwọn olùtọ́jú. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà àìsàn náà kò le tí ọmọ náà sì lè gba ìtọ́jú ní ilé tàbí pẹ̀lú àtìlẹ́yìn Dókítà, àkọ́ṣẹ́mọṣẹ́ apòògùn tàbí olùbẹ̀wò ìlera. Ṣàbẹ̀wò sí wẹ́bsáìtì NHS fún àmọ̀ràn síwájú síi:
**www.nhs.uk/conditions/baby/health**

Irú ìwé ìléwọ́ yìí tí ó tóbi wà nílẹ̀ àti ní èdè oríṣiríṣi.

Jọ̀wọ́ kàn sí:
communications@selondonics.nhs.uk

Ìtẹ̀wéjáde láti East Lonon Integrated care Board

NHS
South East London